# Ọmọ Adam pe Mi ni opurọ, ko si tọ fun un, o si bu mi, ko si tọ fun un

Lati ọdọ Abu Hurairah- ki Ọlọhun yọnu si i-: Ojiṣẹ Ọlọhun, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – sọ pe: “Ọlọhun sọ pe: Ọmọ Adam pe Mi ni opurọ, ko si tọ fun un, o si bu mi, ko si tọ fun un, pipe ti o pe Mi ni opurọ ni ọrọ rẹ ti o sọ pe: Ko lee da mi pada gẹgẹ bi O ṣe da mi ni akọkọ, akọkọ ẹ̀dá ko si rọrùn fun mi ju dida a pada lọ, ṣùgbọ́n èébú tí ó bu Mi ni ọrọ rẹ ti o sọ pe: Ọlọhun ni ọmọ, Ọkan ṣi ni Mi, Ajironukan ni Mi, Mi o bímọ, wọn o si bi Mi, ko si si ẹni kan ti o jọ Mi".

[O ni alaafia] [Bukhaariy gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣàlàyé ninu haiisi kudsiy pe Ọlọhun ti O lágbára ti O gbọnngbọn sọ nípa àwọn ọṣẹbọ ati awọn Kèfèrí pe wọn n pe Oun ni opurọ, wọn si n ròyìn Rẹ pẹlu abuku, ìyẹn ko si tọ fun wọn. Nipa pipe E ni opurọ ni: ero wọn pe Ọlọhun ko lee da wọn pada lẹyin iku wọn gẹgẹ bi O ṣe da wọn ni akọkọ lati ibi àìsí, O wa fesi fun wọn pe Ẹni ti O bẹrẹ dida ẹ̀dá lati ibi àìsí ni ikapa lati da wọn pada, koda oun ni o rọrùn jù, bi o ti lẹ je pe bákan náà ni mejeeji ṣe ri ni ọdọ Ọlọhun ati dida ati dida pada, Ọlọhun ni ikapa lórí gbogbo nnkan. Ni ti eebu wọn: oun ni ọrọ wọn pe: O ni ọmọ, O wa fesi fun wọn pe Ọkan ni Oun, Oun si da ni gbogbo pipe nibi awọn orukọ Rẹ ati awọn iroyin Rẹ, ati awọn iṣẹ Rẹ, O mọ kuro nibi gbogbo àléébù, Ajironukan ni ti ko bukaata si ẹni kankan, ti gbogbo èèyàn si n bukaata si I, ko bi ọmọ kankan, ko si jẹ ọmọ fun ẹni kankan, ko si si ẹni ti o jọ Ọ, mimọ ni fun Un.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/6327

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee